Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 6, nº Especial III | p.116-133 | agosto 2026.

Language: Yorùbá

## Ọ̀rọ̀ jẹ́ńdà àti ìjákọní nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù

**Adewale Lukman ADEMUYIWA (PhD)**
Department of Linguistics and African Languages
Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Osun State, Nigeria.
E-mail: adewaleademuyiwa5@gmail.com & alademuyiwa@oauife.edu.ng
ORCID iD https://orcid.org/0009-0004-8977-4957

**ÀṢAMỌ`**
Àwọn ẹ̀dá ènìyàn tí ó bá kó ipa tí ó ta yọ láàrin àwùjọ ni àwọn Yorùbá ń pè ní akọni. Lọ́pọ̀ ìgbà, àwọn ọkùnrin ni àwùjọ máa ń fojú sùn nígbà tí wọ́n bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìjákọni nítorí ìgbàgbọ́ wọn nípa pé agbára ti ọkùnrin ju ti obìnrin lọ. Àwọn afọ̀ ẹnú Yorùbá fi hàn ìjákọni ọkùnrin àti obìnrin nípa wíwo ipa wọn nínú àwùjọ. Ọ̀kan nínú àwọn akéwì tí ó ṣe àgbéjáde irúfẹ́ afọ̀ yìí ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí ó jẹ́ gbajúgbajà ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Nípa fífi èdè Yorùbá ké ewì fún àwọn olùgbọ́ rẹ̀, ọ̀rọ̀ nípa jẹ́ńdà àti ìjákọni máa ń jẹ yọ ewì rẹ̀. Ìlepá ìṣẹ́ yìí ni láti wo ìjẹyọ akọnìyàn àti abonìyàn gẹ́gẹ́ bí akọnikùnrin àti akọnibìnrin nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Iṣẹ́ yìí ṣe àmúlò àwọn àṣàyàn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù, ó sì ṣe ìtúpalẹ̀ wọn ní ìlànà tíọ́rì Jẹ́ńdà Ajẹmọ́-Ojúṣe ti Judith Butler (Judith Butler’s Gender Performativity Theory). Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí ó hàn pé a lè tọ́ka sí akọnikùnrin àti akọnibìnrin nípa ṣíṣe àkíyèsí àbùdá wọn láàrin àwùjọ. Lára àwọn àbùdá bẹ́ẹ̀ tí iṣẹ́ yìí ṣe àfàyọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni ogun, ìjà jíjà, àyà níní, owó níní, òògùn níní, ipò nínú ìṣèlú, ipò nínú ẹ̀sìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**KÓKÓ Ọ`RỌ`**
Akọnibnrin, Akọnikùnrin, Ewì, Jẹ́ńdà, Ọláńrewájú Adépọ̀jù

## Gênero e sexualidade na poesia do poeta multifacetado

**Resumo**
Os iorubás chamam de heróis as pessoas que desempenham um papel de destaque na sociedade. Frequentemente, a sociedade concentra-se nos homens ao falar de poder, devido à crença de que eles são mais poderosos do que as mulheres. Os poetas iorubás retratam o poder de homens e mulheres ao observar seus papéis na sociedade. Um dos poetas que aborda essa temática de poder é Olanrewaju Adépoju, um poeta popular na Nigéria. Ao utilizar a língua iorubá para recitar poesia ao seu público, ele frequentemente destaca em sua obra a questão de gênero e poder. O objetivo deste estudo é examinar a representação de heróis e heroínas como tais na poesia de Olanrewaju Adépoju. O estudo utiliza poemas selecionados de Olanrewaju Adépoju e os analisa à luz da Teoria da Performatividade de Gênero de Judith Butler. A pesquisa demonstra que heróis e heroínas podem ser identificados pela observação de suas características na sociedade. Entre essas características destacadas na poesia de Olanrewaju Adépoju, encontram-se a guerra, o combate, a coragem, a posse de recursos financeiros, o domínio de conhecimentos medicinais ou mágicos (medicina tradicional), o status político, o status religioso, entre outras.

**PALAVRAS-CHAVE**
Herói, Heroína, Poesia, Gênero, O Maior Herói, Ọláńrewájú Adépọ̀jù

**Gender and heronic issues in Ọláńrewájú Adépọ̀jù's poems**

**ABSTRACT**
Humans who have played outstanding roles in Yoruba society are known as 'akoni,' a Yoruba word that means "hero" or "heroine" in English. Usually, society considers men with certain unique attributes to be at the centre of heroic issues, so they occupy a large public space because it is believed that their strength is dominant when compared to women's. However, Yorùbá verbal arts take a dimension that projects some men and women as great people based on their social performances. One of such arts is by Olánrewájú Adépòju, a prolific Nigerian poet. Reaching his audience through his Yoruba language, he conveys heroic information focusing on gender issues. To exemplify illustrate, this paper examines the depiction of male and female genders as heroes and heroines in his selected poems and analyses the literary compositions within the framework of Judith Butler's Gender Performativity Theory, which claims that heroes and heroines can be identified through the observation of their attributes. This paper analyzes the poet's development of the themes of war, fighting, bravery, financial affluence, charms, politics, and religion to highlight all specific heroic deeds of men and women in the selected texts.

**KEYWORDS**
Hero, Heroine, Gender, Ọláńrewájú Adépọ̀jù, Poems

**Ìfáárà**

Ọ̀kan nínú ohun tí ó jẹ́ àbùdá àti òfin ìṣùwà ẹ̀dá ènìyàn láàrin àwùjọ ni àìdọ́gba àwọn ènìyàn tí ó wà nínú àwùjọ. Èyí ni pé kì í ṣe ìpele kan náà ni àwọn ẹ̀dá inú àwùjọ máa ń wà nítorí àwọn ẹ̀dá kan máa ń ta yọ láàrin àwùjọ. Onírúúrú òṣùnwọ̀n ni a lè fi ṣe ìgbéléwọ̀n ipò tí ẹ̀dá kan wà nínú àwùjọ. Bí a bá wo àbùdá ètó-ọrọ̀ ajé, a lè rí àwọn ẹ̀dá bí mẹ̀kúnnù, kò-là-kò-ṣagbe àti àwọn aládàáńlá tàbí àwọn olówó. Lára ohun tí ó máa ń mú kí àwọn ẹ̀dá inú àwùjọ kan ta yọ àwọn ẹ̀dá mìíràn ni ìwà akínkanjú àti jíjẹ́ akọni. Àwọn tí wọ́n jẹ́ akínkanjú tàbí akọni ni àwọn ẹ̀dá tí ó ní àbùdá tàbí nǹkan pàtàkì tí ó mú wọn ta yọ àwọn ẹ̀dá àwùjọ yòókù. Èyí lè jẹ́ àbùdá tí ó jẹ mọ́ agbára ìlò ara, ọ̀pọ̀ òògùn, owó níní, ènìyàn mímọ̀, ẹwà arà, ọgbọ́n-orí, ipò ẹbí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ọ̀rọ̀ nípa jíjẹ akọni kì í ṣe ohun tí ó ṣọ mọ́ ẹ̀yà jẹ́ńdà kan ṣoṣo; takọtabo ni ó lè jẹ́ akọni láàrin àwùjọ. Èyí fi hàn pé àtilẹ̀ṣe jíjẹ́ akọ tàbí abo (sex) yàtọ̀ sí àtilẹ̀ṣe jẹ́ńdà nítorí pé jíjẹ́ akọ tàbí abo yàtọ̀ sí jẹ́ńdà. Ada gẹ́gẹ́ bí Ude (2006: 1) ṣe tọ́ka sí i, sọ pé:

> Gender is different from sex because it is not biologically determined. While one's sex does not change gender roles can change from culture to culture over time.
>
> (Jẹ́ńdà yàtọ̀ sí ẹ̀yà jíjẹ́ akọ tàbí abo nítorí jẹ́ńdà kò kan àbímọ́. Nígbà tí ẹ̀yà akọ tàbí abo kò lè yí padà, ojúṣe jẹ́ńdà lè yí padà láti inú àṣà kan sí ìkejì ní ìgbàkúùgbà).

Èrò Ada yìí àti èrò Ajíbádé fara pẹ́ ara wọn. Ohun tí Ajíbádè (2009: 2) sọ ni pé:

> Gender refers to the differences between men and women (Masculinity and feminity) that are socially constructed; and sex refers to the biological differences between males and females.
> (Jẹ́ńdà jẹ́ mọ́ ìyàtọ̀ láàrin akọnìyàn àti abonìyàn (ìjákọ tàbí ìjábo) ní ìlànà ètò àwùjọ; ẹ̀yà akọ àti abo (sex) sì jẹ́ mọ́ ìyàtọ̀ àbùdá àbímọ́ akọnìyàn àti abonìyàn).

Kókó-ọ̀rọ̀ méjì ni a rí fàyọ nínú ọ̀rọ̀ Ada gẹ́gẹ́ bí ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin jẹ́ńdà àti ẹ̀yà akọ àti abo. Àkọ́kọ́ ni pé jẹ́ńdà le yí padà ṣùgbọ́n jíjẹ́ akọ tàbí abo kò le yí padà, èkejì ni pé ètò àwùjọ ni jẹ́ńdà nígbà tí jíjẹ́ akọ àti abo jẹ́ àbímọ́. Ọ̀kan nínú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ méjì yìí ló jẹ yọ nínú àkíyèsí Ajíbádé, èyí ni pé ètò àwùjọ ni jẹ́ńdà, àbùdá àbímọ́ sì ní jíjẹ́ akọ tàbí abo.

Ojú tí àwùjọ máa ń fi wò ó lọ́pọ̀ ìgbà ni pé ọ̀dọ̀ àwọn akọnìyàn ni agbára àti ìjákọni fi sí. Ajíbádé (2001) sọ pé ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa pé ọmọkùnrin máa ń le, wọ́n sì máa ń jẹ́ alágbára àti akíkanjú máa ń fara hàn nínú oríkì àbísọ tí wọ́n máa ń sọ ọmọkùnrin. Ajíbádé (2001: 90-96) fi èyí hàn nígbà tí ó sọ pé:

> In Yorùbá society, men are regarded as more powerful than women. That is why they say "Ibi to le là ń bá ọkùnrin" meaning, a man is met in a tough condition or difficult situation. There is another Yorùbá philosophical saying that "Ọkùnrin làkọ̀, ọkùnrin làdá, ẹni tó tún gbági ìdí ẹ mu gan-an, ọkùnrin ní í ṣe, meaning man is cutlass, man si quiver, even the person holding its wooden handle is a man.
>
> (Ní àwùjọ Yorùbá, wọn gba ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó lágbára ju obìnrin lọ. Èyí ló sì fà á tí wọ́n fi máa ń sọ pé "ibi tó bá le là á ba ọkùnrin". Òwe Yorùbá mìíràn tún sọ pé "ọkùnrin làkọ, ọkùnrin làdá, ẹni tó tún gbági ìdí ẹ̀ mú gan-an, ọkùnrin ní í ṣe").

Ohun tí Ajíbádé fi ń hàn ni pé ojú alágbára àti onìyànjú ènìyàn ni àwọn Yorùbá máa ń fi wo ọmọkùnrin, èyí sì máa ń jẹ yọ nínú oríkì ti wọ́n máa ń sọ ọmọ. Èrò yìí náà jẹ́ yọ́ nínú àlàyé Adelegan (2007: 3) tó sọ pé; "Mothers are the agents of peaceful change; fathers are the agents and weapons of war". (Àwọn ìyá jẹ́ ẹni tó máa ń lépa àlàáfíà; àwọn baba sì jẹ́ atọ́kùn àti èròjà ogun). Àlàyé Adélẹ́gàn lọ pẹ̀lú òwe Yorùbá tó sọ pé ibi tó bá le là á bá ọkùnrin. Èyí ni pé nígbà tí àwọn obìnrin bá ń lépa aláàfíà ìlú eré ogun ni àwọn ọkùnrin máa ń sá tàbí kí wọ́n sì máa hùwà tó le. Èyí ń fi ìwà akíkanjú àti ìgbóyà ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí ó ti ń jẹ yọ láàrin àwùjọ hàn.

Àkíyèsí Ọlásùpọ̀, Olúgbèmí àti Adéníran (2012: 13) ni pé nípasẹ̀ agbára àti akíkánjú tí àwọn ọkùnrin ní ni wọn fi gba orí mọ́ àwọn obìnrin lọ́wọ́. Wọn sọ pé:

> Males have taken advantages of females weakness, especially in the act of carring pregnancies and nursing of children, during which time they became less active, female had thus resolved to limit themselves to less strenuus roles.
>
> (Àwọn ọkùnrin ti lo àǹfààní àìlágbára àwọn obìnrin, pàápàá jùlọ nípasẹ̀ oyún níní àti ọmọ títọ́, léyìí tó jẹ́ pé wọn kì í ní agbára lásìkò yìí, èyí sì mú kí àwọn obìnrin gba ohun tí ó lẹ gẹ́gẹ́ bí ojúṣe wọn).

Ohun tí Ọlásùpọ̀, Olúgbèmí àti Adéníran ń sọ ni pé oyún níní àti ọmọ títọ́ ló dín agbára àwọn obìnrin kù, àtipé àǹfààní agbára obìnrin tí ó dínkù nípasẹ̀ oyún níní àti ọmọ títọ́ yìí ni àwọn ọkùnrin fi gborí mọ́ wọn lọ́wọ́, tí àwọn obìnrin náà sì rí ara wọn

gẹ́gẹ́ bí ẹni tí kò ni agbára tí ó tó agbára ọkùnrin. Wọ́n tún tẹ̀síwájú pé; "However, society erroneously accepted this as societal value and thus felt that there are male and female roles". (Bákan náà, àwùjọ ṣe àṣìṣe gbígbà á gẹ́gẹ́ bí àṣà àwùjọ èyí sì jẹ́ kí wọ́n rò pé ọkùnrin ni ipa obìnrin náà sì ni ipa (èyí tí ó yàtọ̀ sí ara wọn). Ìtumọ̀ èyí ni pé gbígbà pé agbára ọkùnrin ju ti obìnrin lọ ti di ètò àti àṣà àwùjọ; bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àṣìṣe ni èyí nínú èrò Ọlásùpọ̀, Olúgbèmí àti Adéníran (2012).

Lára ohun tí ó máa ń jẹ́ ìlépa ẹ̀dá yálà lọ́kùnrin tàbí lóbìnrin ni láti ni ipa nínú àwùjọ tí ó bá wà. Ìlépa yìí ni ó sì máa ń fi àwọn akọni hàn sí ayé gẹ́gẹ́ bí akínkanjú ẹ̀dá láàrin àwùjọ. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kì í ṣe ojú kan ni a lè fi wo ẹ̀dá ènìyàn gẹ́gẹ́ bí akọni. Èyí túmọ̀ sí pé onírúurú ọ̀nà ni ènìyàn lè gbà di akọni. Olówó lè jẹ́ akọni nínú owó níná, ológun lè di akọni nínú ogun jíjà, olóògùn lè di akọni nínú ewé jíjá, olóṣèlú si lè di akọni òṣèlú, akọni ìdí ẹ̀sìn wà, akọni onísòwò sì wà pẹ̀lú, bákan náà ni ènìyàn le di akọni nípa ìjìjàgbara. Ohun tí ó jẹ iṣẹ́ ìwádìí yìí lógún ni wíwo ọ̀rọ̀ nípa akọni akọnìyàn àti abonìyàn nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Òté wíwo èyí sì ni àgbéyẹ̀wò àwọn ohun tí akèwí tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí orígun àṣeyọrí wọn.

**Tíọ́rì Àmúlò – Tíọ́rì Jẹ́ńdà Ajẹmọ́-Ojúṣe ti Judith Butler (Judith Butler's Gender Performativity Theory)**

Tíọ́rì tí iṣẹ́ ìwádìí yìí yàn fún ìtúpalẹ̀ ni tíọ́rì Jẹ́ńdà Ajẹmọ́-Ojúṣe ti Judith Butler (Judith Butler's Gender Performativity Theory). Tíọ́rì yìí jẹ́ tíọ́rì tí Judith Butler pilẹ̀ rẹ̀ ní ọdún 1990, èyí tí ó ń fúnka mọ́ àgbéyẹ̀wò ojúṣe ẹnìkan tàbí ẹ̀yà jẹ́ńdà kan láàrin àwùjọ nípa àṣetúnṣe akitiyan wọn àti ipa tí wọn ń kó nínú àwùjọ. Àwọn onímọ̀ mìíràn tí wọ́n tún ṣe iṣẹ́ lórí tíọ́rì yìí ni Llyod (1999), Salih (2002) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Tíọ́rì yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé jẹ́ńdà kì í ṣe ohun tí ẹnìkan jẹ́ gan-an, bí kò ṣe ipa tí ẹnìkan kó tàbí ohun tí ẹnìkan gbé ṣe láàrin àwùjọ. Butler (1990, 1993) ṣe àlàyé pé kò sí nǹkan kan ní ìpìlẹ̀ ìṣẹ̀dá ọmọnìyàn tàbí ohun tí ó jẹ mọ́ pàtàkì akọnìyàn tàbí abonìyàn tí ó jẹ́ okùnfà ìṣe tàbí ìhùwàsí ajẹmọ́-jẹ́ńdà nínú àwùjọ.

Pàtàkì ìṣàmúlò tíọ́rì yìí fún iṣẹ́ yìí ni ọ̀rọ̀ nípa pé ìwà tí ẹnìkan bá hu láàrin àwùjọ, tí ó sì ń ṣe lemọ́lemọ́, ni yóò jẹ́ kí ó tayọ láàrin àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀. Èyí ni pé kì í ṣe pé jíjẹ́ akọ tàbí abo ni yóò sọ ipò ènìyàn nínú àwùjọ bí kò ṣe ipa tí ènìyàn bá kó. Ní ìbámú pẹ̀lú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ àti ní ọ̀gangan iṣẹ́ yìí, tíọ́rì yóọ́ jẹ́ kí a lè ṣe àfàyọ àwọn ipa ribiribi tí àwọn ẹ̀dá ń kó láàrin àwùjọ, èyí tí ó sọ wọn di akọni àti ìjẹ̀yọ irúfẹ́ àwọn ẹ̀dá bẹ́ẹ̀ lọ́kùnrin àti lóbìnrin nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù.

**Aáyan Ọmọ̀ràn Ìṣáájú lórí Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù**

Lára àwọn onímọ̀ tí ó ti ṣe iṣẹ́ lórí ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni Fọ́lọ́runsọ́ (1997, 1999), Bọ́dúnde (2001), Okùnoyè (2010, 2011), Adéyẹmọ (2011), Àjàyí (2014), Adémùyíwá (2014) àti Ogundipe (2014). Iṣẹ́ Fọ́lọ́runsọ́ (1997) lórí ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù dá lórí àwọn ọ̀rọ̀ òṣèlú tí ó máa ń jẹ yọ nínú ewì rẹ̀. Bí ó ṣe tì ń fi yìn àwọn olóṣèlú àti bí ó ṣe ń lo ewì rẹ̀ láti polongo ìbò fún wọn.

Bọ́dúndé (2001) ṣe àgbéyẹ̀wò kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmóṣèlú nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. O ṣàlàyé ipa ti ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ń kó lórí ètò ìṣèlú àwùjọ. Àwọn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí ó lò fún ìṣàtúpalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀ yìí ni *ìpinnu* àti *kádàrá* tí wọ́n jáde lọ́dún 1993, lásìkò rògbòdìyàn ìbò M.K.O Abiọla; June 12, 1993. Bọ́dúndé tọ́ka sí ipa tí àwọn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù yìí kó lórí rògbòdìyàn yìí, ó sì gbà pé ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ wà lára òhun tí ó ń ṣe ìrànwọ́ ìmúgbóòrò àwọn akéwì òde-òní. Nínú iṣẹ́ náà, Bọ́dúndé tun tọ́ka sí bí Ọláńrewájú Adépọ̀jù ti ṣe fi ewì ṣàfihàn ìmọ̀lára àwùjọ lórí ìjọba Babangida àti ìlànà ètò ìṣèjọba rẹ̀. Ohun tí o jẹ kókó-ọ̀rọ̀ inú iṣẹ́ Bọ́dúndé yìí náà ni ipa ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù lórí ètò ìṣèlú àwùjọ.

Okúnoyé (2011) ṣàlàyé pé ó tó bí ogóji ọdún ṣẹ́yìn tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí ń kéwì. O sì tọ́kà sí Ọláńrewájú Adépọ̀jù gẹ́gẹ́ bí ojúlówó akéwì tí ó dáńtọ́. Nínú iṣẹ́ yìí, Okùnoyè wo ìjẹyọ ìmúgbòòrò àṣà nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Ó sì tún wo ipa ti ẹ̀sìn ni lórí ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Àlàyé Okùnoyè nì pé kò sí àfihàn ẹ̀sìn tí kì í jẹ yọ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Ó ti kéwì fún ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀ rí, kí ó tó wá gbájú mọ́ ewì ajẹmẹ́sìn Mùsùlùmí. Nínú iṣẹ́ yìí, ọ̀kan-ò-jọ̀kan kókó-ọ̀rọ̀ tí ó máa ń jẹ yọ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni Okùnoyè tọ́ka sí, o sì tún  wo bí ìyípadà ṣe ń bá ewì rẹ̀ ní àtìgbàdégbà. Okùnoyè (2011) tún ṣe àmúlò gbèdéke àkóónú láti pín ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù sí sáà méjì ọtọọtọ. Sáà kìn-ín-ní ni láti ọdún 1960 sí 1980, tí ó tí ń kéwì pẹ̀lú àkóónú tó jẹ́ mọ́ àṣà Yorùbá, ìwà ọmọlúàbí, àti àwọn ètò àwùjọ mìíràn. Sáà kejì ni o ti tọ́ka sì pé ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ti jẹ́ mọ́ àkóónú ajẹmẹ́sìn. Sáà yìí bẹ̀rẹ̀ láti ọdún 1981.

Adéyẹmọ́ (2011) nínú iṣẹ́ rẹ̀ tí ó pé ní *ìtúpalẹ̀ kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́-ìṣèlú nínú ewì Yorùbá láti inú fónrán àti apìlẹ̀kọ* náà tọ́ka sí Ọláńrewájú Adépọ̀jù nínú àwọn akéwì tí ó ṣàyàn. Kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmóṣèlú ni Adéyẹmọ́ náà sì gbájumọ́ nínú iṣẹ́ ọ̀hún. Òun náà ṣàfihàn Ọláńrewájú Adépọ̀jù gẹ́gẹ́ bí akéwì tí ọ̀rọ̀ òṣèlú kì í fara sin nínú ewì rẹ̀.

Adémúyìwá (2014:158) ṣàlàyé nínú iṣẹ́ náà pé:

> Àkíyèsí wa ni pé àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ takọtabo máa ń jẹ yọ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Àwọn Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "kò sí ẹni máa-nì-ín-lára, àpọ̀jù rẹ̀ ni kò sunwọ̀n". Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ yìí jẹ mọ́ dídára àti àìdára akọnìyàn àti abonìyàn, yíyìn akọnìyàn àti abonìyàn, títọ́ka sí àléèbù takọtabo àti ojú àmúwayé Ọláńrewájú Adépọ̀jù nípa akọnìyàn àti abonìyàn.

Èrò Adémúyìwá nínú iṣẹ́ yìí ni pé Ọláńrewájú Adépọ̀jù kì í ṣegbè lẹ́yìn akọ tàbí abo, ewì rẹ̀ wà láti tọ́ka sì àléèbù, àmúyẹ, àti ìbáṣepọ̀ takọtabo, èyí sì lọ ni ìlànà tíọ̀rì àbùdá oníbejì takọtabo. Adémúyìwá (2017) wo abala ìmọ̀ ìṣọwọ́lò-èdè nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù, èyí tí ó gbára lé ìlànà ìfojú-ìhun-wò, àwòmọ́hun ni ó wo ìṣọwọ́lò-èdè Ọláńrewájú Adépọ̀jù nínú àwọn ewì rẹ̀ tí ó gbé jáde lórí fọ́nrán.

Àjàyí (2014) ṣe àfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ bí ìlérí òfo àwọn olóṣèlú, àpọ́nlé síse, ọ̀rọ̀ nípa ikú, ìkìlọ̀, ọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ ṣíṣe, ìmọ̀ tara ẹni nìkan, ìdìtẹ̀, ìpànìyàn, ọ̀wọ́n gógó epo bẹntìróò àti ẹ̀kọ́-ilé. Àwọn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí ó fi ṣàwòta nínú iṣẹ́ náà ni *Ọ̀rọ̀ oṣèlú*, *Tèmí yémi*, *ikú Awólọ́wọ̀* àti *Àṣàyàn ọ̀rọ̀*. Ọ̀rọ̀ òṣèlú ni iṣẹ́ tìrẹ̀ yìí náà gbára lé.

Ògúndípẹ̀ (2014) lórí ìgbéjáde àti ọnà ìṣẹ̀dá ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni àtìgbàdégbà àti àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmẹ́sìn inú ewì rẹ̀. Ògúndípẹ̀ wo bí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́ ẹ̀sìn Mùsùlùmí tí ń jẹ yọ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù àti ipa tí àwọn kókó-ọ̀rọ̀-ajẹmẹ́sìn náà ni lórí ìgbéjáde ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. O gbà pé ọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn Mùsùlùmí jẹ́ ọ̀kan nínú kókó-ọ̀rọ̀ tí o máa ń jẹ́ olúborí nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù.

Ọ̀nà mẹ́rin ni a lè pín gbogbo akìtìyan àwọn onímọ̀ ìṣáájú tí a gbé yẹ̀wò yìí sí gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n ṣe. Àwọn ọ̀nà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà ni kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmẹ́sìn, kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmóṣèlú, ọ̀rọ̀ nípa jẹ́ńdà àti ìmọ̀ ìṣọwọ́lò-èdè. Ọ̀rọ̀ ìṣèlú ni o rí ipa akìtìyan àwọn onímọ̀ yìí dáadaa lẹ́yìn náà ni ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, iṣẹ́ Adémùyíwá (2014) nìkan ló dá lórí jẹ́ńdà. Àgbéyẹ̀wò ọ̀rọ̀ akọnìyàn àti abonìyàn gẹ́gẹ́ bí akọni nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni ó jẹ́ àfojúsùn iṣẹ́ ìwádìí yìí. èyí yóò sì ṣe àfikún sí ìmọ̀ tí ó wà nílẹ̀ lórí ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù.

## Àbùdá Ìjákọni

Ènìyàn kì í ṣàdéédé di akọni láàrin àwùjọ Akínwùmí àti Adémúyìwá (2024: 22) jẹ́ kí ó hàn pé ìka ẹ̀dá kò dọ́gba, àti pé ó máa ń ni àwọn àbùdá tí àwọn ẹ̀dá àwùjọ fi máa ń ta ara wọn yọ. Àkíyèsí wọn ni pé:

> Gẹ́gẹ́ bí ó tí jẹ́ pé ìka ò dọ́gba láàrin àwùjọ ẹ̀dá ènìyàn, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ó jẹ́ pé àjùlọ àti ìtayọ máa ń jẹ́ yọ nínú ipò àti àbùdá àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú àwọn ìwé ìtàn àròsọ. Èyí ni pé bí a bá wo ipò tí ẹ̀dá-ìtàn kan wà nínú ìtàn, àti àwọn àbùdá tí òǹkọ̀wé gbé wọ̀ wọ́n lọ́rùn, ó hàn pé ààyè kan náà kọ́ ni àwọn ẹ̀dá-ìtàn máa ń wà, àjùlọ àti ìtàyọ máa ń fojú hàn nínú ipa àti ojúṣe wọn nínú ìtàn.

Àrífàyọ inú àyọlò òkè yìí ni pé òṣùwọ̀n kan náà kọ́ ni a lè fi wọn àwọn ẹ̀dá ènìyàn láàrin àwùjọ, àjùlọ wọn yìí sì máa ń hàn nínú àgbékalẹ̀ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ni Akínwùmí àti Adémúyìwá (2024) tọ́ka sí nínú àlàyé wọn òkè yìí, síbẹ̀, ìtọ́kasí àjùlọ láàrin àwùjọ kì í ṣe ohun tí ó faraṣin nínú lítíréṣọ̀ ajẹmohùn Yorùbá náà.

Ohun tí ẹ̀dá kan bá fi tayọ àwọn ẹ̀dá mìíràn láàrin àwùjọ náà ni ó máa ń sọ ẹ̀dá ọ̀hún di akọni. Ọ̀rọ̀ nípa jíjẹ́ akọni kò sì ṣeé fi ojú ẹ̀gbẹ́ kan wò. Èyí hàn nínú àlàyé Bowra (1952: 91) sọ pé:

> … This does not mean that all heroes are of a single kind. Just as there is more than one kind of human excellence, so there is more than one kind of hero. The different kinds reflect not only different stages of social development but the different metaphysical and theoretical outlooks which the conception of a hero presupposes.
> (Èyí kò túmọ̀ sí pé bákan náà ni gbogbo àwọn akọni. Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ́ pé ìlànà àṣeyọrí ẹ̀dá ju ẹyọ̀kan ṣoṣo lọ, bẹ́ẹ̀ náà ọ̀nà ìjákọni ju ẹyọ̀kan lọ. Oníruurú tí wọ́n jẹ́ kì í ṣe nípasẹ̀ ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìpèlè ìmúgbòòrò àwùjọ nìkan, ṣùgbọ́n ìyàtọ̀ nípa ohun àìfojúrí àti ìlànà nípa wíwo ohun tí ìjẹ́kọni jẹ́ gan-an.)

Àlàyé Bowra (1952) òkè yìí fi hàn pé ojú ẹ̀gbẹ́ kan ṣoṣo kọ ni a lè fi wo àbùdá ìjákọni láàrin àwùjọ. Èyí tí ó túmọ̀ sí pé nǹkan ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó lè sọ ẹnìkọ̀ọ̀kan di akọni. Bíòbákú (1973: 43) tọ́ka sí oníran-ǹ-ran àwọn irúfẹ́ àbùdá tí ó lè sọ ènìyàn di akọni láàrin àwùjọ nígbà tí ó sọ pe:

> There are certain characteristics of heroes. These includes super-natural or marvelous birth, endangered childhood, prodigious feats in manhood; successful overcoming of danger and trials; acquisition of a hidden treasures; winning a bride or liberating a captive damsel and finally a heroic death.
>
> (Àwọn àbùdá kan wà fún àwọn akọni. Èyí kan ìbíni ní àrà ọ̀tọ̀, wíwà nínú ewu nígbà èwe, kí ènìyàn kó ipa mánigbàgbé, ìjàjàbọ́ nínú ewu àti ìlàkàkà, kíkó ọrọ̀ tí ó faraṣin jọ, gbígba ìyàwó tàbí títú ẹni tí ó wà nínú ìgbèkùn sílẹ̀ àti ní pàápàá, kí ènìyàn kú ikú akọni.

Àrífàyọ inú àlàyé Bíòbákú (1973) òkè yìí ni pé lára àwọn àbùdá tí ó ń sọ ènìyàn di akọni láàrin àwùjọ ni ìforílakú, ìbíni bí àkàndá-ẹ̀dá, ọrọ̀ níní, níní ìyàwó, gbígba ẹ̀mí là àti kíkú ikú akọni. Bí a bá tún àwọn àbùdá yìí yiiri wò, a lè sọ pé ènìyàn lè di akọni nípasẹ̀ níní ìrírí, jíjẹ́ jagunjagun, níní òògun, akitiyan nínú ètò ìṣèlú, owó níní àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àkíyèsí sì fi hàn pé takọtabo ni ó lè ni irúfẹ́ àbùdá ìjákọni yìí, kì í ṣe ohun tí ó so mọ́ ẹ̀yà jẹ́ńdà kan ṣoṣo.

Àjùwọ̀n (2017: 80) tilẹ̀ gbà pé àbùdá tí ó wuyì láti pín àwọn sí ìṣọ̀rí ni wíwo jẹ́ńdà wọn nígbà tí ó sọ pé:

> ...a rí i pé òṣùwọ̀n tó lóòrìn láti fi pín àwọn akọni náà sí ìsọ̀rí ni lílo àbùdá-takọ-tabo (jẹ́ńdà) láti pín wọn sí ìsọ̀rí méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Nítorí náà, oríṣìí ẹ̀yà akọni méjì tó wà ni akọni-bìnrin àti akọni-kùnrin. Abẹ́ àwọn ẹ̀yà akọni méjèèjì yìí ni a ti lè rí ìsọ̀rí àwọn akọni mìíràn bíi akọni àjẹbí, akọni-dòrìṣà, akọni ìgbà-ìwáṣẹ̀, akọni òde-ọ̀run, akọni àjogúnbá, akọni gbajúmọ̀ àti akọni agbójúlé-bọ̀rọ̀kìnní tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn onímọ̀ náà menu bà.

Àrífayọ̀ inú àlàyé Àjùwọ̀n (2017) òkè yìí ni pé lílo ìlànà jẹ́ńdà láti pín akọni sí ìsọ̀rí yóò jẹ́ kí ó hàn kedere pé takọtabo ni ó lè jẹ́ akọni.

**Ìjákọni àti Jẹ́ńdà**

Gbogbo ẹ̀dá inú àwùjọ ni ó lè jẹ́ akọni. Akọ́ní lè wà nínú àwọn ọ̀dọ́ (èyí hàn nínú Rabiu 2025), akọni sì lè wà nínú àwọn àgbàlagbà. Ní ìpìlẹ̀, ọ̀rọ̀ tí àwọn Yorùbá ń pè ní akọni jẹ́ ohun tó jẹ mọ́ akọ, ìdí ni pé ìtumọ̀ rẹ̀ ni akọ + ẹni = akọẹni = akọni (Adémùyíwá 2014). Bí a bá tẹ̀lé ìlànà ìhun ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ yìí, ohun tí ó fi hàn ni pé akọnìyàn nìkan ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí akọni ṣùgbọ́n èyí kò fi kò ìdí múlẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá nítorí ọ̀pọ̀ obìnrin ni a rí ìtọkasí wọn gẹ́gẹ́ bí akọni (Àjùwọ̀n 2017). Adémùyíwá (2014: 185) ṣe àlàyé ṣíwájú nípa èyí pé:

> Èyí ni pé ohun tó jẹ akọni ní í ṣe pẹ̀lú ẹ̀dá tí ó bá jẹ́ akọni ní ìpìlẹ̀. Ṣùgbọ́n kì í ṣe akọnìyàn nìkan ni wọ́n ń fojú akọni wò láwùjọ Yorùbá, wọ́n gbà pé akọni wà nínú abonìyàn náà gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú akọnìyàn. Bí obìnrin bá jẹ́ akíkanjú tan, àwọn Yorùbá a tilẹ̀ máa pè é ní "Obìnrin bí ọkùnrin".

Bí ó ti wà ní Lìkì náà ló wà ni Gbàǹja, kì í ṣe ojú kan ni a lè fi wo abonìyàn náà gẹ́gẹ́ bí akọni. Onírúurú ọ̀nà ni obìnrin náà le gbà jẹ́ akọni. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Àjùwọ̀n (2017: 277) pé:

> ...Ohun tí èyí ṣàfihàn ni pé kò sí bí igun ṣe ṣẹ orí tí ọbọ kò ṣe ìdí, igún pá lórí, ọ̀bọ náà sì pá ní ìdí. Kò sí ojú àbùdá ìjákọni tí a le fi wo àwọn akọnikùnrin tí a kò le fi wo àwọn akọnibìnrin náà. Wọ́n sì ń lo agbára ìjákọni wọn láti ṣàgbágbè ara wọn láàárín àwùjọ ni.

Àlàyé Àjùwọ̀n (2017) òkè yìí fi hàn pé agbára ìjákọni láàrin àwùjọ kò kan jẹ́ńdà. Ipa tí ènìyàn bá kó láàrin àwùjọ ni yóò fi onítọ̀hún hàn bóyá ó jẹ́ akọni tàbí kì í ṣe akọni.

**Ìjákọni Akọnìyàn nínú Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù**

Akọnikùnrin ni àwọn ọkùnrin tí wọ́n kó ipa mánigbàgbé nínú àwùjọ. Wọ́n jẹ́ ọ̀wọ́ àwọn ọkùnrin tí wọ́n ti fi ara wọn hàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá tí ó tayọ láàrin àwùjọ. Oxford (2006 :700) sọ nípa akọnikùnrin tí ó pè ní '*hero*' pé; "a person who engaged in brave deeds with a great determination to succeed or to achieve something difficult" (ẹni tí ó ń hùwà ìgboyà pẹ̀lú ìlépa láti ṣe àṣeyọrí tàbí láti mú èròǹgbà rẹ̀ nípa ohun tí ó bá le koko wá sí ìmuṣẹ).

**Owó Níní**

Akọni olówó ni ènìyàn tó jẹ́ gbajúgbajà nínú olówó láàrin àwùjọ. Irú akọni bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ jẹ́ ẹni tí kò gba ọ̀nà èrú lówó tí ó sì ń lo owó rẹ̀ sọ́nà rere. Nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí ó pè ní "Abínú-Ẹni" Ó fi Olóyè M.K.O. Abíọ́lá hàn gẹ́gẹ́ bí akọni olówó. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ewì náà pé:

Bólówó bá ń bọra wọn lọ́wọ́
Ó lójú ẹni tí Kásìmawò jẹ́ nawọ́ sí
Tara gbígbéga kọ́
Mo fẹ́ kó yé gbogbo wa
Kẹlẹ́gbẹ́ ó mẹgbẹ́ ni
Igimú jìnnà sórí
Ẹ wí fún ẹlẹ́gàn kó yéé yẹ̀gẹ̀ ètè
Mọ̀súdì Kásìmawòò Ọláwálé ọmọ Abíọ́lá
O dámi lójú ọwọ́ ọ̀já gùn jọwọ́ aṣọ lọ
Ọ̀rọ̀ àwàdà kọ́, ọmọ Abíọ́lá ò ṣe rogbodo  lásán
Orí ló kẹ́ Mọ̀súdì.

Àyọlò ewì òkè yìí fi ń hàn pé olóyè M.K.O. Abíọ́lá lówó ta yọ àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀. Èyí ni pé akọni nínú olówó ni, èyí tí ó sì mú un tí ó fi jẹ́ pé kì í ṣe gbogbo olówó ló le dúró bọ Kásìmawòò lọ́wọ́. Bákan náà, Ọláńrewájú Adépọ̀jù tún gbà pé akọni olówó ni Mufutau Ọlánínhún. Ó gbà pé náwónáwó olówó ni. Ó sọ nínú ojúkejì ewì “Ìsípayá” pé:

Mufu Láninhún lẹni àkòlọ́nà-ta-kìjí
Náwónáwó tí í bu náírà bí ẹ̀wà ọ̀sọ̀sọ̀
Ọkùnrin ogun ni Mufu
Bó selé bó soko
Tèwe tàgbà ní í sápẹ́ wo lîlí
Gbogbo ayé ní í wòye òsùpá
Múfú ń kọjá lọ́nà wọ́n ń dìgbò lura wọn.
Wọn fẹ́ rí Múfú kó tó kọjá lọ
Ọ̀jọ̀ ńlá
Olówó tí í mìgboro tìtì

Ewì òkè yìí fi hàn pé olówó ni Mufu Lánínhún, náwónáwó sì ni pẹ̀lú, nítorí náà, akọni olówó ní í ṣe. Ó tún hàn bí tẹrú tọmọ ṣe máa ń sùùrù bo Múfú Lánínhún nínú ewì náà. Ohun tí ó sì fa ṣábàbí agbo tí wọ́n ń pa yí i ka ni owó tí ó máa ń ná fún wọn.

## Ogun Jíjà

Ọkan nínú àbùdá pàtàkì tí èniyàn lè gbà di akọni ní àwùjọ Yorùbá ni jíjẹ́ akínkanjú ní ìdí iṣẹ́ ogun jíjà. Akọni ni àwọn Yorùbá gba ẹni tí ó bá mọ ète ogun jíjà sí láàrin àwùjọ. Èyí hàn nínú àlàyé Àjùwọ̀n (2017: 27) tí ó sọ pé:

> Iṣẹ́-ogun ló máa ń sáábà sọ àwọn ọkùnrin di akọni. Lóòótọ́, kì í ṣe gbogbo àwọn Balógun tó ti jẹ ní ilẹ̀ Yorùbá ni a mọ̀ sí akọni, ṣùgbọ́n, gbogbo àwọn tí wọ́n jẹ́ Ààrẹ-Ogun láyé àtijọ́ ni wọ́n jẹ́ akọni. Àwọn akọni ọkùnrin yìí ni wọ́n máa ń gba ìlú wọn sílẹ̀ lọ́wọ́ ogun, ọ̀tẹ̀ tàbí làásìgbò tó bá wọ ìlú wọn wá.

Akọni ológun ni jagunjagun tí ó ń jagun fún ìdáàbò bò ìlú. Irú wọn sì gbọ́dọ̀ jẹ́ àjagunségun. Ṣe àwọn Yorùbá bọ̀, wọ́n ni “ojú-ogun ni a ti ń mọ Balógun to gbójú”. Bí èniyàn kò bá tî jagun wò, bó ṣe  wù kó mọ ète ogun jíjà tó, àwùjọ kò le pè é ní akínkanjú tàbí akọni ológun. Ọláńrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí akọni ogun ìgbàanì. Èyí ni jagunjagun ìbílẹ̀ ní ìlànà àṣà Yorùbá gan-an nípa lílo èròjà oògùn àti ète ogun jíjà. Lára irú àwọn akọni jagunjagun báyìí ni Àfọ̀njá gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú ewì *Èdè Àìyedè*. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ewì náà pé:

Àfọ̀njà

Lọ́kọláyà
Alùgbìnrìn ọ̀tẹ̀
Lo jólórí ogun nígbà náà

Ó hàn nínú ìtàn tí ó pa nínú ewì náà pé akọni àti ògbójú ènìyàn ni Àfọ̀njá, ṣùgbọ́n àrè tí ó fàáyè gbà ni ó fa ìjákulẹ̀ rẹ̀. Yàtọ̀ sí Àfọ̀njá tí ó jẹ́ akọni ìgbàanì, Ọláńrewájú Adépọ̀jù tún ṣe àfihàn ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí akọni ní ìlanà jíjẹ́ jagunjagun ìgbàlódé èyí tí ó jẹ mọ́ lílo ìbọn, bọ́ǹbù àti oníruúrú ète ogun jíjà. Ọláńrewájú Adépọ̀jù fi General Muritala Muhammed hàn gẹ́gẹ́ bí akọni ológun, ó sọ nínú ojú kìn-ín-ní ewì tí ó pe orúkọ rẹ̀ ní *Gen. Muritala* pé:

Múrítàláá
Jagun a rìn pìrìpìrì bi kílẹ̀ẹ́lẹ̀ ó lójú
Mọ́námọ́ná sọ́jà tí í rìn toguntogun
Wèrèpè fi gbogbo ara sòkè ìjà gbọ̀ingbọ̀nìn
Múrítàlá a dógun jà lẹ́yìn ẹni tó logun
Arógun dúró
Akọni ogun
Olórí ogun
Àgbà ogun
Ìbẹ̀rù ogun
Kìkì ogun
Ọkùnrin dùgbẹ̀dùgbẹ̀ bí igi àdárọ̀.

Èyí fi hàn pé nínú ìlànà ogun jíjà ti ìbílẹ̀ àti ìgbàlódé ni àwọn àwọn ọkùnrin ti fakọyọ ní àwùjọ Yorùbá, èyí sì hàn nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù.

**Òògùn Níní**

Àkọni olóògùn ni akọni tó jẹ́ pé nípasẹ̀ ewé jíjá àti egbò wíwà ni ó fi di akọni. Irú akọni bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ògbójú-olóògùn-kan-ọmọ-àjẹ́-níkòó, ó sì gbọ́dọ̀ máa lo òògùn rẹ̀ ní ọ̀nà rere. Irú akọni báyìí ni Daniel Kayọde Mákinde tí gbogbo ènìyàn mọ̀ sí Adúlójú. Ọláńrewájú Adépọ̀jù ṣe agbékalẹ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni olóògùn. Ó tílẹ̀ sọ ìtàn rẹ̀ ni ojú kìn-ín-ní àwo ewì tí ó pè àkọlé rẹ̀ ni *Ibi orí Dáni sí* pé wọ́n bí i mọ́ ewé ni, èyí ni pé wọn bá ewé tútù lọ́wọ́ rẹ̀ nígbà tí wọ́n bí i, ní kékéré. Èyí fi hàn pé ó mú iṣẹ́ ìṣègùn ti ọ̀run wá sáyé ni. Bákan náà ni ó tún jẹ́ pé nǹkan ìyanu ṣẹlẹ̀ nígbà Adúlójú kú. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ewì náà pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Adúlójú di onígbàgbọ́, síbẹ̀ kò pa iṣẹ́ ìṣègùn rẹ̀ lára, bẹ́ẹ̀ sì ni ìṣègùn kò pa ẹ̀sìn rẹ̀ lára. Èyí ló jẹ́ kí Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ewì *Ibi orí Dáni sí* pé:

Ó ń ṣiṣẹ́ ìṣègùn
Ó ń ṣisẹ́ ìgbàgbọ́
Tewétegbo ló fi ń tún tàwọn aráyé ṣe
Àgbàlagbà ìṣègùn tó wá ṣiṣẹ́ àánú láyé
Mákindé tí kì í ṣòògùn ìkà
…
Ìgbàgbọ́ oníṣègùn
Tí í pe sátánì níjà

Àyọlò òkè yìí ṣe àfihàn Daniel Káyọ̀dé Mákindé tí gbogbo ènìyàn mọ̀ sí Adúlójú, ẹni tí ó jẹ́ ọmọ bíbí agbègbè Èkìtì ní ilẹ̀ Yorùbá hàn gẹ́gẹ́ bí akọni nínú iṣẹ́ ìṣègùn nítorí pé ó ní ìmọ̀ kíkún nípa tewétegbò, èyí tí ó jẹ́ ìlànà ìṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá.

**Ètò Ìṣèlú**

Akọni òṣèlú ni olóṣèlú tí ó jẹ́ gbajúgbajà nínú ètò ìṣèlú, tí ó sì lo agbára rẹ̀ fún ìtẹ̀síwájú àti ìmúgbòòrò àwùjọ. Akọni òṣèlú gbọdọ̀ jẹ́ olóṣèlú tí ó nípa rere láàrin àwùjọ, orúkọ rẹ̀ kò sì bàjẹ́ nínú àwùjọ tí ó ti jáde wá. Irú olóṣèlú bẹ́ẹ̀ ni Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nípa rẹ̀ nínú ewì *Ikú Awólọ́wọ̀* báyìí pé:

Ọbáfẹ́mi
Aṣòoróná bí owó Ìjẹ̀bú
Baba Ọmọtọ́lá tí í ràn bí òsùpá
Ẹni tí wọn ń kọminú ẹ̀
Tí ò kọminú wọn
Ọ̀fẹrẹngẹ bi iná baba Olúṣẹ́gun
Ò da jìnnìjìnnì bọmọ àlejò
Ikú mólorí aláwọ̀dúdú lọ
Ò sinmọ débi ẹ̀rù
Àlùjànnú nínú olóṣèlú àgbáyé
Baba Olúwọlé gbókìkí rọ̀run.
Ojú dá poo
Ojo pà pà tíí jin sàréè lójú
Ọmọ Màríà
…
Ikú pa ẹni ìyàtọ̀ nínú olóṣèlú
Ojú dá
Àbí ò dá?

Ohun tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù fẹ́ kí á mọ̀ nípa Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ nínú ewì òkè yìí ni pé akọni òṣèlú ni Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ jẹ́ nígbà ayé rẹ̀. Ìdí nìyí tí ó fi pè é ní "Àlùjànnú nínú olóṣèlú àgbáyé". Bákan náà ni ó tún pe Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ni "ẹni ìyàtọ̀ nínú olóṣèlú". Àbùdá ìyàtọ̀ tí ó fi ṣe àfihàn Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ yìí gan-an ni ó sàfihàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni. Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ du ipò ààrẹ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ṣùgbọ́n kò rí ààrẹ jẹ́, síbẹ̀, èyí kò yọ ọ́ kúrò nínú jíjẹ́ akọni nítorí àwọn ipa mánigbàgbé tí ó ti kó ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, pàápàá jùlọ, ní àṣìkò tí ó jẹ́ olórí ìjọba ẹkùn ìwọ̀-oòrùn orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àtijọ́ (South-Western Premier). Àwọn akọnìyàn mìíràn tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù rí bí akọni òṣèlú ní àwùjọ Yorùbá àti ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni Ọládòkè Akíntọ́lá, Adélabú Pẹnkẹlẹméẹ̀sì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ yọ nínú àwọn ewì rẹ̀ mìíràn.

## Jíjà fún Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn

Akọni ajìjàgbara ni àwọn akọni tó ṣe pé ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ni àwọn máa ń jà fún. Irú àwọn akọni báyìí kì í fààyè gba ìrẹ́jẹ, wọn kì í sì jẹ́ kí esinsinkésinsin bá le ohun tí ó bá wà ní ṣàkáání wọn. Irú akọnìyàn báyìí tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù mẹ́nu bà ni Fẹlá Aníkúlápó Kutì tí ó jẹ́ gbajúgbajà ọ̀kọrin ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ̀rọ̀ nípa Fẹlá Aníkúlápó Kutì nínú ewì *Ayé Tótó*, níbi tí ó ti kéwì pé kí wọn tú Fẹlá sílẹ̀ kúrò nínú àtìmọ́lé nítorí pé ó ń jà fún ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn. Èyí jẹ́ kí ó hàn pé kò sí ohun tí ojú ajìjàgbara kì í rí tán. Wọn lè tì wọ́n mọ́lé, wọ́n sì le tì í wọ́n wọ ẹ̀wọn, kódà, wọ́n lè gba ọ̀nà ẹ̀bùrú pa wọ́n. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ewì *Ayé Tótó* pé:

Ìjọba sójà ẹ̀bẹ̀ la bẹ̀ yín
Ẹ wá bá wa dárí jin Fẹlá Aníkúlápó
Gbogbo ayé ló ń fẹ́ Fẹlá bí ọmọ tuntun
Ojúlówó ọmọ Nàìjíríà
Tó tọ́ ka máa mú yangàn gbá à ni
Ẹ̀bẹ̀ gidi là ń bẹ̀ sọ́jà
Kó tú Fẹlá sílẹ̀ nínú ẹ̀wọ̀n
Fẹlá Anikulapo
Ẹni Gẹ̀ẹ́sì ń gbé láruge

Tí Amẹ́ríkà ń yọ̀ọ́ mọ́
Tí Faraṣé mọ̀ lọ́kùnrin ogun
Ọba olórí orin Áfúró tó lórúkọ níbi gbogbo

Àkíyèsí ni pé orin afuró ni Fẹlá Aníkúlápó ń lò gẹ́gẹ́ bí agbára tàbí idà láti jà fún ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn. Nípasẹ̀ èyí, Fẹlá ṣe kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ bẹ́ẹ̀ di ìlú-mọ̀-mí-ká olórin Áfúró (Afro), tí orin rẹ̀ fi hàn gẹ́gẹ́ bí ajìjàgbara.

**Ẹ̀sìn**

Akọni ẹ̀sìn ni àwọn tí ó jẹ́ pé ní ìdí ẹ̀sìn ni wọ́n ti di olórúkọ àti olókìkí. Ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn ní ó máa ń múmú láyà àwọn wọ̀nyí, àwọn ni wọ́n sì máa ń dàbí agbòòrùn tí ó máa ń di gàgá ẹ̀sìn wọn. Àkíyèsí ni pé kò sí ẹ̀sìn kan tí kò ni akọni tirẹ̀. Ọláńrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí Olóògbé Olùsọ́-Àgùtàn S.P.J. Ọ̀ṣọfà tí ó jẹ́ olùdásílẹ̀ ìjọ Celestial Chruch of Christ gẹ́gẹ́ bí akọni ènìyàn nínú ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn-Jẹ́ṣù. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ojú kìn-ín-ní ewì *Ọ̀fin Mẹ́wàá* pé:

Ọ̀ṣọfà to dolókìkì àpèkáyé
Olóòtú ìjọ mímọ́ ni baba
Apatapìtì ìgbàgbọ́ tí í ba sátánì lẹ́rù
Nilé ladìẹ ò gbé ti níyì
Bó bá yọ síbòmímràn nínlá ló jẹ́
Ṣe torí pé kì í ṣàwọ̀ funfun ló gbé sára ni?
O gbà
O ò gbàgbọ́ o
Wòlíì lọmọ Àlàkẹ́
Ó dá mi lójú púpọ̀púpọ̀
Àsọtẹ́lẹ̀ tiẹ̀ tó bá sọ
Gẹ́gẹ́ ní í gún kì í tàsé
Ẹ ṣe bí wòlíì yẹpẹrẹ lásán ni
Ìkìlọ̀ to ṣe fórílẹ̀ èdè Bìnnì lọ́jọ́sí
Ó yí wọn lọ́wọ́ tán díẹ̀ ló kù

Àkíyèsí Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni pé a kò le tìtorí pé Ọ̀ṣọfà kì í ṣe òyìnbó ká wá sọ pé kì í ṣe akọni wòlíì nínú ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn-Jẹ́ṣù. Ó gbà pé o gbójú, ó gbónu, ó sì máa ń sọ àsọtẹ́lẹ̀. Àwọn nǹkan wọ̀nyí sì ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù gbà pé ó jẹ́ àbùdá jíjẹ́ akọni nínú ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn-Jẹ́ṣù.

Bákan náà, nínú ẹ̀sìn Mùsùlùmí, Ọláńrewájú Adépọ̀jù gbà pé akọni ènìyàn ni Sheu Mustapha Mubarak Aṣílé ti ìlú Ìlerò. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nípa Sheu yìí nínú ojú kejì awo *Àtubọ̀tán Ayé* pé:

Mo rántí Sheu Mustapha Mubarak
Ọ̀kan nínú Mùsùlùmí tó dáńgájí
Tó ń tọ súnà
Tó ń sòótọ́
Irú ẹni a mọ̀ ni Sheu nù un
Níbi to jagun ẹ̀sìn àsìnlà dé láyé
Ọba Yárábì ló lè san án ní láádá
Ó ré kọjá ohun à á ròyìn
…
Bó jẹ́ pé ti kéú
Níbi ká sì máa ṣẹ̀sìn àsìnlà ní déédé
Ká tọ́ni sọ́nà nílànà ẹ̀sìn mímọ́
Bó bá tún jẹ ti ká sì máa fòfin yé ni

Ọ̀gá ni Mustapha Ìlerò
Nínú ẹni Ọba Yárábì ń lò

Pẹ̀lú àlàyé tó hàn nínú ewì òkè yìí, ó hàn pé Ọláńrewájú Adépọ̀jù gbà pé akọni ọkùnrin ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí ni Sheu Mustapha Ìlerò ń ṣe. Àwọn àbùdá tí ó sọ ọ́ di akọni inú ẹ̀sìn Mùsùlùmí gẹ́gẹ́ bí Ọláńrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí i ni pé ṣe ẹ̀sìn ní déédé, ó ń tọ́ni sọ́nà nílànà ẹ̀sìn Mùsùlùmí, ó la òfin ẹ̀sìn yé àwọn ènìyàn, Ọlọ́un sì ń lò ó. Bákan náà, Ọláńrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí Fáṣínà Àkànó Agboọlá gẹ́gẹ́ bí akọni nínú ẹ̀sìn ìbílẹ̀. Ó sọ̀rọ̀ nípa Agboọlá pé akọni ẹlẹ́sìn Ifá ni nínú ewì *Tèmi ń Bẹ Lára Mi*. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ pé:

Agbooọlá dífá dífá
Iṣẹ́ Ifá pé
Àkànó sísẹ́ ìṣègùn débi tárísìkí wà
Ó ti fòótọ́ inú ṣòwò ọ̀pẹ̀lẹ̀
Ó tẹ́ḿbẹ́lú awo àrígbàjẹ
Èèyàn tórí wọn bá fẹ́ ṣe láǹfààní
Ní í bẹ Fásínà létùtù
…
Ṣe bí ẹ rí irú Agboọlá
Tó ń fi gbogbo ifá tó ń dá sisẹ́ láádá
Aṣọ olówó-ńlá lọmọ Fátókí fi ń bora
Aṣawo-ṣẹ̀ṣẹ̀gùn
Tí í ṣọṣẹ ọlà fótòṣì ènìyàn

Ọláńrewájú Adépọ̀jù gbà pé iṣẹ́ rere ni Agboọlá Fásínà ń fi Ifá rẹ̀ ṣe. Àwọn ohun tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nípa Agboọlá yìí fi hàn pé akọni ẹlẹ́sìn Ifá ni. Lára àwọn àbùdá náà ni pé ó ṣe ẹ̀sìn ní owó lọ́wọ́, ó ń fi òtítọ́ inú dá Ifá, ó ń fi Ifá ṣe iṣẹ́ àánú fún àwọn ènìyàn, bí ó sì ṣe ń ṣe awo Ifá ni ó tún ń ṣe iṣẹ́ ìṣègùn, èyí tí ó fi hàn pé Fásínà tún jẹ́ akọni oníṣègùn.

**Òwò Ṣíṣe**

Akọni ìṣòwò ni ẹni tí ó ṣòwò tí ó bóde pàdé, tí ó ti ibi ìṣòwò rẹ̀ di ọlọ́rọ̀, tí ó sì di olókìkí. Irú oníṣòwò bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ jẹ́ ẹni tí ó ti fara da gbogbo ìṣoro tí ó kojú rẹ̀ lóko ìṣòwò rẹ̀. Nínú ojú kìn-ín-ní ewì *Ayé Tótó*, Ọláńrewájú Adépọ̀jù fi orin ewì ki Làsísì Sànúsí gẹ́gẹ́ bí akọni oníṣòwò. Ó sọ pé:

Ìwà rere
Ìwà ìrẹ̀lẹ̀ ń bẹ fÁkàndé òdí
Tó rówó ta mọ́tò
Tó sì jèrè
Ọmọ Sànúsí fọlá mìgboro tìtì
Àkàndé, akọ ẹran tí í jà bí ògìdán
Lóógun àdúgbò
Ìjì baba afẹ́fẹ́ tí í dági lóko
Bọ̀rọ̀kìnní tí ń ta mọ́tò
Tí ń pawó tútù sápò
…
Bàbá Tàòfíkì
Ìwọ lo lòwò
Àkàndé, máa kérè ọjà wálé

Àkíyèsí ni pé ṣìṣòwòjèrè ni ohun tí ó sọ Làsísì Sànúsí di akọni ìṣòwò, bákan náà sì ni ó jẹ́ akíkanjú tí ó ní òkìkí níbi òwò ọkọ̀ títà.

**Ìjákọni Aboniyàn nínú Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù**

Akọnibìnrin ni àwọn obìnrin tí wọ́n kó ipa mánigbàgbé nínú àwùjọ. Wọ́n jẹ́ ọ̀wọ́ àwọn obìnrin tí jíjẹ́ obìnrin wọn kò mú àdínkù bá agbára àtilèṣe nǹkan mánigbàgbé tí ó sọ wọ́n di akọni. Oxford (2006: 700) sọ nípa akọnibìnrin tí ó pè ní '*Heroine*' pé; "a female brave and great person of real or mythical who carries out extra-ordinary deeds" (obìnrin tí ó ní ìgboyà, tí ó sì jẹ́ ẹni ńlá yálà nínú ìtàn gidi tàbí ìtàn-ìwáṣẹ̀, èyí tí ó ṣe ohun tí ó tayọ). Obìnrin lè jẹ́ akọni olówó, akọni ológun, akọni ọ̀ṣèlú, akọni ìṣòwò, níní ìgboyà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Owó Níní**

Ọláńrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí arábìnrin Nímọ́tà Àyìnkẹ́ Abẹ̀rùàgbà bí akọni olówó, ó gbà pé olótìítọ́ ènìyàn ni pẹ̀lú. Ó sọ ní ojú kejì ewì tí ó pè ní *Ayé Tótó* pé:

Gbogbo ọ̀nà tá a bá ń rìn láyé
Ó tọ́ ká bá ni nídìí òótọ́
Ó mú mi rántí màmá pàtàkì kan
Tó lówó lọ́wọ́
Tó lágbára bí ọba
Ta ni ò gbọ́ nípa Nímọ́tà Ayinkẹ Abẹ̀rù-àgbà
Tí gbogbo ayé ń pókìkí ẹ

Èyí fi hàn pé Ọláńrewájú Adépọ̀jù gbà pé takọtabo ní orí dá ní olówó láàrin àwùjọ, kì í ṣe ọkùnrin nìkan ni a le rí gẹ́gẹ́ bí akọni olówó. Bákan náà ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí Abíọ́dún Àmíná gẹ́gẹ́ bí akọnibìnrin tí ó jẹ́ olówó. Ó gbà pé ṣàṣà ènìyàn ni ó le bá Àmíná Abíọ́dún fi ẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ nínú owó níná. Ó sọ nínú ewì *Tèmi ń Bẹ Lára Mi* pé:

Àkọ̀yìnsí Àmíná
Owó
Ìdúró Àmíná
Owó
Ẹ̀rín Àmíná
Owó
Ìjà Àmíná
Owó
Itọ́ Àmíná
Owó
Kẹ̀lẹ̀bẹ̀ Àmíná
Owó
Towótowó lÀmíná ń jí
Towótowó lÀmíná ń sùn

Kókó-ọ̀rọ̀ ohun tí akéwì ń sọ nínú ewì náà ni pé owó pọ̀ fún Àmíná dé ibi pé ó rí owó ṣe ohun gbogbo. Èyí sì jẹ́ kí ó hàn pé akọni obìnrin olówó ni Àmíná Abíọ́dún.

**Òwò Ṣíṣe**

Ọláńrewájú Adépọ̀jù gbà pé ó wà nínú àwọn aboniyàn tí ó jẹ́ akọni nínú ìṣòwò. Lára irú àwọn bẹ́ẹ̀ tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù mẹ́nu bà ni Àṣàbí Bello tí ó jẹ́ oníṣòwò pàtàkì. Ó sọ nípa rẹ̀ nínú ewì *Àlàyée Kádàrá* pé:

Ìyá ẹgbẹ́ onísìgá
Ṣe bí gbangba nìyọ òsùpá
Bórí bá jólórí ọlọ́lá

Kádàrá kò kúkú ní ṣẹ́
...
Ìbàdàn lAdaniwaye kọ̀dí ire ìyá Mórílìátù sí
Ó wá jáfínjú ọlọ́jà lọ́jà Amúnígun
Aṣíwájú Ìyálájé Aare Ìbàdàn lÀṣàbí
Níńlá nínú ọlọ́jà tó ṣòwò jèrè

Àkíyèsí ni pé bí ènìyàn bá ṣòwò dé ibi tí ó ṣe àṣejèrè, tí ó sì joyè nídìí òwò ọ̀hún; akọni níí ṣe. Bákan náà, Ọláńrewájú Adépọ̀jù tún tọ́ka sí Nímọ́tà Àyìnkẹ́ Abẹ̀rù-àgbà gẹ́gẹ́ bí akọni ìsòwò tí ó ṣòwò, tí ó jèrè, tí ó bóde pàdé. Bákan náà ni akéwì tún sọ nípa rẹ̀ bí ó ṣe dá ilé-iṣẹ́ sílẹ̀ tí àwọn ènìyàn sì ń ṣe iṣẹ́ ní abẹ́ rẹ̀. Ó sọ nínú ewì ojú kejì *Ayé Toto* pé:

Àyìnkẹ́ ọmọ Abẹ̀rù-àgbà wá ní owó náà tán
Ó ṣe pabanbarì fárá orílẹ̀-èdè yìí
O kọ́lé iṣẹ́ ńlá sí Ìjẹ̀bú-Òde
Ilé-iṣẹ́ tó ń hunṣọ tó ní lááŕí
Tí wọ́n gbé gbọmọ aráyé ṣíṣẹ́ lọ kánrin
Ibiṣẹ́ tó ń jẹ́ Low lenghty Lane
Àyìnkẹ́ ló dáléeṣẹ́ náà sílẹ̀

Bí ènìyàn bá le dá ilé-iṣẹ́ sílẹ̀ sí orílẹ̀-èdè rẹ̀, tí ó gbá àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè ọ̀hún síṣẹ́ níbẹ̀, tí ó sì ń pèsè ohun tí ó wúlò fún orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀, oníṣòwò ní akọniyàn sì ni pẹ̀lú. Àkíyèsí òkè yìí ni ó sì jẹ́ kí Ọlánrewájú Adépọ̀jù tọ́ka sí Nímọ́tà Àyìnkẹ́ Abẹ̀rù-àgbà gẹ́gẹ́ bí akọni ìṣòwò.

### Ètò Ìṣèlú

Lóòótọ́ ló jẹ́ pé àwọn ọkùnrin ló hànde jù nínú ètò ìṣèlú ilẹ̀ Yorùbá àti ti Adúláwọ̀ lápapọ̀; yálà nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ tàbí ti ìgbàlódé, ṣùgbọ́n ipa àwọn aboǹiyàn náà kò farasin nínú ètò ìṣèlú ilẹ̀ Yorùbá yálà ní ti ìbílẹ̀ tàbí ti ìgbàlódé. Nínú ewì "Ọmọ Odùduwà" ní ojú kejì, Ọláńrewájú Adépọ̀jù ké sí àwọn akọni òṣèlú ilẹ̀ Yorùbá láti wà ní ìsọ̀kan, kí wọ́n sì parí dúkùú tí ó bá wà láàrin wọn. Lẹ́yìn náà ni ó pe àwọn akọni àgbà òṣèlú kan láti mójútó aáwọ̀ tí ó wà láàrin àwọn òṣèlú ilẹ̀ Yorùbá. Nínú àwọn tó dárúkọ ni arábìnrin Taibat Ọdúnewu wà. Nínú ewì *Ọmọ Odùduwà*, Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ pé:

Ọ̀rọ̀ àarin Olúbùnmi Ògúndípẹ̀ pẹ̀lú ọlọ́lá Jákànńdè
Ẹ tara mójú tó o,
Baba wa Ọsọ́lọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́lá Fágbèmí Àjànàkú
Ẹ yanjú ẹ lásìkò
Ọba Adéyínká Oyèékàn ẹ dá sí i
Iyálájé Èkó
Ẹniire tí í jẹ́ Táìbátù Ọdúnewu
Ẹyin àgbààgbà ń bẹ lọ́jà
Bórí ọmọ tuntun bá wọ́ kò wúlò

Nínú àyọlò òkè yìí, Ọláńrewájú Adépọ̀jù ké sí àwọn akọni òṣèlú ilẹ̀ Yorùbá láti wà ní ìsọ̀kan. Bí akéwì ṣe dárúkọ Táìbátù Ọdúnewu nínú àwọn àgbà òṣèlú pé kí wọ́n pẹ̀tù sí aáwọ̀ tí ó wà láàrin Olúbùnmi Ògúndípẹ̀ àti Lateef Jákànńdè fi hàn pé ènìyàn pàtàkì láwùjọ àwọn àgbà òṣèlù ni Ìyálájé Táìbátù Ọdúnewu.

### Akọni Ogun

Ìgbàgbọ́ àwùjọ Yorùbá ni pé gbogbo iṣẹ́ tí ó bá le láàrin àwùjọYorùbá ní í jẹ́ ti ìran ọkùnrin. Lára irú iṣẹ́ líle bẹ́ẹ̀ sì ni ogun jíjà wà. Ṣùgbọ́n bógun bá le tán, àwọn obìnrin a máa kún àwọn ọkùnrin nípá láti ja ogun. Lílọ sí ojú ogun obìnrin máa ń ni ìdí pàtó. Lọ́pọ̀ ìgbà kì í ṣe láti jà bí kò ṣe láti máa tọ́jú àwọn tó ń fara pa, tàbí pípèsè oúnjẹ fún àwọn tó ń jagun. Èyóówù kó jẹ́, akọni ní í lọ sí ojú ogun, ojo ènìyàn kọ́. Irú àwọn ẹ̀dá tí ó jẹ́ akọbìnrin báyìí ni Arábìnrin Àmíná Abíọ́dún tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù ménu ba akitiyan rẹ̀ lójú ogun. Àwo ewì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ méjì ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù ti kéwì nípa ìgbìyànjú arábìnrin yìí, nínú ewì *Tèmi ń Bẹ Lára Mi* àti ewì *Ìtẹ̀síwájú*. Ohun tí ìyá yìí ń ṣe lójú ogun ni pé ó ń pèsè oúnjẹ fún àwọn tó ń jagun. Àkíyèsí ni pé orígun ojúṣe takọtabo fara hàn nínú irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí, àwọn ọkùnrin n jagun àwọn obìnrin ń dáná oúnjẹ fún wọn. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nínú ewì *Tèmi ń Bẹ Lára Mi* pé:

Ìyànjú owó ló gbà tí tí tí
To fi tẹ̀lé sọ́jà lọ sójú ogun
Olúwa Ọba ló jẹ́ kó yọ nínú ewu ogun
Aálà ni o fààyá ṣe déédé Àmínátù.

Ohun tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù fẹ́ ká mọ̀ ni pé akọnibìnrin ni Àmíná, àtipé ó láyà dé ibi pé ó bá àwọn sọ́jà lọ sí ojú ogun. Àkíyèsí ni pé iṣẹ́ tí Àmíná Abíọ́dún ṣe yìí jọ iṣẹ́ tí Ẹfúnroyè Tinúùbú ṣe láàrin Ẹgbá tí ó fún àwọn ọkùnrin ni ìṣírí ogun, tí ó sì ń tọ́jú àwọn tí ó fara pa títí tí wọn fi ja ogun náà ní àjàṣẹ́gun. Ìtàn nípa Ẹfúnroyè Tinúùbú yìí hàn nínú Ìṣọ̀lá (1983).

**Níní Ìgbóyà**

Ó hàn pé àwọn akọni kan wà tí wọ́n jẹ́ ògbójú akọni. Ògbójú akọni tí à ń sọ níbí ni irúfẹ́ àwọn ènìyàn tí ó jẹ́ pé wọ́n ní ìgboyà láti ṣe ohunkóhun tí wọ́n bá fẹ́ ṣe láìsí ìdíwọ́ tàbí ìbẹ̀rù ẹnikẹ́ni. Ìtọ́kasí àwọn aboniyàn ti wọ́n ní irú ìgboyà yìí hàn nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù. Lára irú àwọn ẹni bẹ́ẹ̀ tí o fara hàn nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni Fadéya ọmọ Lágelú tí ó tẹ ìlú Ìbàdàn. Fadéya yìí jẹ́ ọmọbìnrin tí ó le, tí ó gbójú, tí ó sí láyà. Ọláńrewájú Adépọ̀jù sọ nípa àyà níní rẹ̀ àti bí ó ṣe ní í ṣe pẹ̀lú ìtàn Ìbàdàn nínú ewì ojú kejì *Àgbà Ọ̀rọ̀*. Ó lọ báyìí:

Lágelú tó tẹ̀lú dó
Ilé-Ifẹ̀ ló ti wá
Lágelú ọba tó bímọ líle
Lágelú náà ló kọ́kọ́ jọba ìlú Ìbàdàn
Ìgbà tó ń tilé Ifẹ̀ẹ́ bọ̀
Ó gbádé lọ́wọ́
Adé náà ló sì fi jọba lórí ọba
Ọ̀rọ̀-apata-ma-ja ló kọ́kọ́ dádé
Nílé Olúyọ̀lé Ìbàdàn
Ọmọ rẹ̀ kan ń bẹ tínú kì í pé bí
Ọmọ ọ̀hún jóbìnrin
Ojoojumọ́ ní í bínú
Gbogbo ọjọ́ ní í ṣaápọn
Ẹnu kì í sìn lára rẹ̀ bí òòṣà
Ọjọ́ to hùwà tó bí baba nínú
Tí Lágelú bọ́mọ rẹ̀ wí láàfin
N lọmọ baba bá bínú kọjáa ti baba
Ibi baba ń gbádé ìlẹ̀kẹ̀ sí
Ló bá wọ ibẹ̀ ló gbádé ìlẹ̀kẹ̀

Kí gbogbo ìjòyè tó kọ ‘Há-hà! Há-hà!’ tán
Ọmọ ti fi ìbínú gbèsan
Ká tó séjú pẹ́
Fẹrẹgẹdẹ lọmọ bínú fadé ya
Bí aré bí àwàdà ló bá sadé dàkísà
…
Gbogbo ìjòyè ló forí kò
Wọ́n fẹ́ gbé e kúrò lọ́kàn baba
Wọn pera wọn jọ wọ́n tojú adé tuntun
Ni Lagelu ba fààké kọ́rí, ó ní ká mẹ́nu kúrò níbẹ̀
Ọ̀rọ̀-apata-ma-ja ló ni bádé bá sogún
Òun ò ní dádé mọ́
Ó ní bádé ṣegba, kádé o máa múra wọn
Ìwọ̀sí lọ̀bá kò to fi ń dé lábàrìkádà
Bí wọ́n bá ń ki Ìbàdàn lọ́mọ Fadéya
Ìdí nù un
Ọba gbádé wá ọmọ ọba ló bínú fadé ya.

Àkíyèsí tí ó wà nínú ìtàn inú àyọlò náà ni pé akọnibìnrin àti ọmọ líle ni Fadéya. Ó lérò nínú ara rẹ̀ pé bàbá òun bá òun wí lọ́nà àìtọ́, ó pinnu láti fi ẹ̀hónú hàn láìwo ti pé òun jẹ́ obìnrin. Ìdí sì nìyí tí ó fi bínú fa adé bàbá rẹ̀ ya lójútáyé. Irú ìpinnu rẹ̀ yìí mú ìyàtọ̀ ńlá bá ètò ìṣèlú ìlú Ìbàdàn, ó sọ ọba Ìbàdàn di ọba tí kì í dé adé mọ́ àfi fìlà kí ó tó di pé Olúbàdàn Gbadamọsi Adébímpé bẹ̀rẹ̀ sí í dé adé padà. Àti pé nípasẹ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni wọ́n ti sọ “Fadéya” ní orúkọ rẹ̀ tó ń jẹ́. Ó hàn pé irú ìwà tí Fadéya hù yìí jẹ́ ìwà akọni. Ìdí ni pé Lágelú gan-an kì í ṣẹran rírọ̀ tí ẹnìkan le gbéná wojú rẹ̀ ní ọ̀sán gangan.

Bákan náà, Ọláńrewájú Adépọ̀jù ṣe àfihàn arábìnrin Mọ́ńdìátù Àmọ̀pé gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó láyà nínú ojú kejì ewì *Edè Àìyedè*. Ó sọ nínú ewì náà pé:

Mo mọ Mọ́ńdìátù Àmọ̀pé sójú
Ká wí pólówó
Tí í dáko tọ́kùnrin ò le ro
Abo tí í fọwọ́ sọ̀yà
Níbi ọkùnrin ti ń tọ̀ sí ṣòkòtò
…
Panápaná ẹjọ́
Obìnrin ń láyà jura wọn lọ
Ẹ wẹ̀yìn wò
Kẹ́ ẹ tó ṣàbòsí ọmọọba
Ìyáa Ṣóbáyọ̀ ń bọ̀.

Àfiwé pàtàkì méjì ni ó fara hàn nínú ewì òkè yìí. Àkọ́kọ́ ni pé Mọ́ńdìátù ń dáko ti ọkùnrin kò le ro, èkejì ni pé “ó ń fọwọ́ sọ̀yà níbi tí ọkùnrin tí ń tọ̀ sí ṣòkòtò”. Ìtumọ̀ tí àwọn ìpèdè yìí ni pé Mọ́ńdìátù ni àyà ju ọkùnrin lọ, ó sì lè dágbá lé ohun tí ọkùnrin gan-an lè má ní àyà láti ṣe.

**Àgbálọgbábọ̀**

Pẹ̀lú àwọn kókó-èrò tí a gbé yẹ̀ wò, àrífàyọ ni pé ojú tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù fi ń wo akọnìyàn gẹ́gẹ́ bí akọni ni o fi ń wo abonìyàn náà, gbogbo àwọn àrímọ́ àti àbùdá tí ó sì mẹ́nu bá gẹ́gẹ́ bí àwòmọ́ tí a fi le gbà pé akọni ni ènìyàn ni ó fi ṣàgbékalẹ̀ akọnìyàn àti abonìyàn nínú àwọn ewì rẹ̀. Iṣẹ́ ìwádìí yìí fi hàn pé kò sí aṣọ akọni tí a dá fún akọnìyàn tí abonìyàn náà kò lè wọ̀. Bí a ṣe lè rí ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí akọni nínú ogun jíjà, àyà níní,

owó níní, òògùn níní, ipò nínú ìṣèlú àti ipò nínú ẹ̀sìn, bẹ́ẹ̀ ni a lè rí abònìyàn náà gẹ́gẹ́ bí akọni nínú akitiyan ogun jíjà, àyà níní, owó níní, òògùn níní, ipò nínú ìṣèlú àti ní ìdí ẹ̀sìn. Èyí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àbùdá jíjẹ́ akọni kò gbára lé ipò tí ènìyàn wà nípa àbùdá ìjákọ tàbí abo tàbí ipò jẹ́ńdà awùjọ tí ènìyàn ti wá, ipa tí ènìyàn bá kó láàriin àwùjọ ni ó máa sọ ènìyàn di akọni.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Adelegan, A. (2007). *Women of Great Virtues*. Lagos: Arigbabowo Publications.

Ademuyiwa, A. L. (2014). "Àgbèyẹ̀wò Ọ̀rọ̀ Jẹ́ńdà nínú Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù". (A Critical Analysis of Thematic and Stylistic Features in Oríkì of Towns in Òkè-Ògùn). Unpublished B.A. Long Essay, Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Ademuyiwa, A.L. (2017). "Ìtúpalẹ̀ Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lò-Èdè nínú Àsàyàn Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù". (A Critical Analysis of Stylistic Features in Selected Ọláńrewájú Adépọ̀jù's Poetry). Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Adéyẹmọ, O. A. (2011). "Ìtúpalẹ̀ Kókó-ọ̀rọ̀ Ajẹmọ́-Ìṣèlú Nínú Ewì Yorùbá láti inú Fọ́nrán àti Àpilẹ̀ko (1990-2009)". Ph.D. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Àjàyí, F. (2014). "Àgbéyẹ̀wò Àṣàyàn Ewì Ajẹmóṣèlú Ọláńrewájú Adépọ̀jù: Àfihàn ìṣẹ̀lẹ̀ Àwùjọ". Nínú *ẸGIN: Jọ́nà iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*.

Ajíbádé, G.O. (2001). "A Socio-Cultural Analysis of Yorùbá Personal Oríkì (Oríkì Àbísọ)" *In Ifẹ̀ Journals of Theory and Research in Education*. Ijotre Vol. 6. No. 1, 90–96.

Ajíbádé, G.O. (2009). Finding female Voice. A Socio-Cultural Appraisal of Yorùbá Nuptial Poetry. Rudiger Koppe Verllag Koln. Germany.

Àjùwọ̀n, J. (2017). "Ìtùpalẹ̀ Àṣàyàn Oríkì àwọn Akọnikùnrin àti Akọnibìnrin Yorùbá ní Ìwọ̀-Oòrùn Orílẹ̀-èdè Nàìjíria", Unpublished Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Akinwumi, P.A. àti Ademuyiwa, A.L. (2024). "Àjùlọ àti Ìjákulẹ̀ Ẹ̀dá-ìtàn nínú àwọn Ìwé Ìtàn- Àròsọ Yorùbá". *LÀÀNGBÀSÀ: Jónà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*, University of Lagos. Number 24. 22–36.

Bíòbákú, S.O (1973). *Sources of Yorùbá History*. Ìbàdàn. O.U.P.

Bódúndé, C. (2001). "Aesthetics, Media and Political Currents in Yoruba Literature" *African Language Literatures and Political context of the 1990's*, Bodunde, C. (ed). Germany: Eckhard Breitinger,

Bowra, C.M (1952): *Heroic Poetry*. New York. Macmillan.

Butler J. (1990). *Gender Trouble: Feminism and the Subversion of Identity.* Routledge.

Butler J. (1993). *Bodies that Matter: On the Discursive Limits of "Sex".* Routledge.

Fọ́lọ́runṣọ́, A. (1997). "Òṣèlú Akéwì nínú Òṣèlú: Àyẹ̀wò Ewì Lánréwájú Adépọ̀jù", *Inquiry in African Languages and Literature*, No. 2, 92–102.

Fọ́lọ́runṣọ́, A. (1999). The written Yoruba Poetry (1949-1989): A study in the Sociology of Literature. A Dissertation. Department of Linguistics and African Languages.

Ìṣọ̀lá, A. (1983). *Olú Ọmọ*. Ìbàdàn: Onibon-Oje Press and Book Industries.

Lloyd, M. (1999). "Performativity, Parody, Politics". *Theory, Culture & Society*. Vol16, no.2., 195–213

Ogundipe, S. (2015). "Hybridity and the Construction of Ọlanrewaju Adepọ̀jù's Poetry", Ph.D. Thesis. Ọbafemi Awolọwọ University. Ile-Ifẹ.

Okunoye, O. (2010). "Ewì, Yoruba Modernity, and the Public Space" *Research in African Literatures*. Vol. 41. No.4, 43–64.

Okunoye, O. (2011). "Lanrewaju Adepọ̀jù and the Making of Mordern Yoruba Poetry" *Africa*. Vol. 81, no.2., 175-203.

Ọlásùpọ̀, A.F., Olúgbèmí, V. àti Adéniran O. (2012). Proverb and Gender Equalities and Equities in African Cultures: Yorùbá Culture as a Case Study. In *Global Journal of Human Social Science: A Arts and Humanities*, U.S.A Volume 12, Issue 13, Verson I.O., 11–26. Oxford Dictionary (2006).

Rabiu, O.F. (2025). "Àgbéyẹ̀wò Ipa àti Ipò àwọn Ọ̀dọ́ nínú Àṣàyàn Iṣẹ́-ọnà Adébáyọ̀ Fálétí". (An Examination of Space and Place of Youths in Selected Works of Adébáyọ̀ Fálétí). Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Salih, S. (2002). *Judith Butler*. Routledge

Ude, A.A (2006). "Introducing the Concept of Gender". Paper presented at 5-Day Capacity Building Workshop on Gender Planning, and budgeting for Local Government Personnel in Nigeria. Organized by the Endowed Chair Centre for Gender and Social Policy, OAU, Ile- Ifè.

## Author's Bio

**Adewale Lukman Ademuyiwa** is a lecturer at the Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria. He took his B.A in Yorùbá, M.A. and Ph.D in Yorùbá Language and Literature from the same university. He also obtained a Nigeria Certificate in Education (N.C.E) in Hausa and Yoruba languages from Oyo State College of Education, Oyo, Oyo state, Nigeria. His research, teaching and publications focus on Yorùbá Oral and Post-colonial Literature, Literary Theories, Stylistics and Criticism.

Recebido em: 03/2026
Aceito em: 30/07/2026

**Para citar este texto (ABNT):** ADEMUYIWA, Adewale Lukman. Ọ̀rọ̀ jẹ́ńdà àti ìjákọní nínú ewì ọláńrewájú adépọ̀jù**.** *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras*. São Francisco do Conde (BA), vol.6, nº Especial III, p.116-133, agosto 2026.

**To cite this text (APA):** Ademuyiwa, Adewale Lukman. (august 2026). Ọ̀rọ̀ jẹ́ńdà àti ìjákọní nínú ewì ọláńrewájú adépọ̀jù**.** *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras*. São Francisco do Conde (BA), 6 (Special III): 116-133.